Chief Secretary to the Govnt.


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. 306 SATURDAY, DECEMBER 22 1928 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

-4 JAN. 1929 LAGOS

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, l o si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.


[signature]

# To Stop Your Aches & Pains

## Simply Use




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept handy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale

Fassett & Johnson, Ltd.

86, Clerkenwell Road,

London, England.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office 24*, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### IṢẸ OKUNKUN WO LEYI?

Ẹni kan rohin ohun ti on ri ni Ileto kan ni ọkan ninu awọn ilu awọn kan t'o mbẹ ni agbegbe Igberiko kan ti ko jinna si Eko: Ọgbẹni na sọpe bi awọn Onişẹ-Ọba pẹlu Oyinbo wọn ti de ilu yi lati bẹrẹ iṣẹ wọn ni mumuṣe, bẹni nwọn lọ sọdọ alagba kan nibẹ ti o wa ni ihoho ọmọ-luwabi nigbati Oyinbo si sọfun pe afara kosi ki o fi aṣọ bo ara rẹ bẹni Ọgbẹni Alagba na wa laye Oyinbo yi pe awọn kan ninu awọn ọta on lo ṣe ogun si on pe lailai on ko ni fi aṣọ bo ara mọ ati pe nigbakigba ti on ba si fi aṣọ bo ara nṣe ni aṣọ na yio ma jo on lara bi ina: o ni ti on ba fi aṣọ sara ni isisiyi gẹgẹbi Oyinbo na ti pa laṣẹ fun on, yio dabi ẹnipe ina ni nwọn da si on lara, ẹnu ya Oyinbo Onişẹ-Ọba yi tobẹ ti o fi sọfun awọn enia ti o mbẹ ni apa ibiti ọkọnrin yi gbe wa ki nwọn kuro nibẹ.

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

### ABỌ O!

Ni ọjọ Alamisi ijẹwa ti nṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni Lọya W. Wells-Palmer, ẹniti o tilọ si ilu oyinbo lati nkan bi oṣu kẹta sẹhin ba ọkọ de si ilẹ yi a si ro wipe alafia li ẹ de.

### A KO I DE 'BI A NRE PỌNBE.

A gbọ wipe nwọn ti da gbogbo awọn elewe-ọmọ ati gbogbo awọn ẹniti o nta ori eku, ori ẹiyẹ ni Ọbun-Eko lọ si Ebute Oko-Awo nibi isọ awọn Aladiẹ lati iwọn bi ọjọ melo sẹhin, a tanma pe ti ile ti awọn Ijọba gba gbogbo ni Idunmọta lo fa sababi yi o.

### ABUDU GIWA.

Ni ọjọ Satide ijẹjọ ni a gbọ ti ọfọ Ọgbẹni Abudu Giwa ti Agọṣofin, Ọlọrun ki o fori ji o, a ki awọn ọmọ oloku nwọn ku ọfọ na.

### ỌDUN DE!

Ni iwoyi ọjọ Atalata ireni loni, a ti bọ si inu ayọ odun Keresimesi, ti ọpọlọpọ enia si ma yọ ayọ rẹ kakiri, nibẹ si ni awọn ẹlomiran bi ọmọ Alikali yio si ma huwa ipata kiri ode, ki Ọlọrun pẹtu si awọn yẹn ninu lọtẹ yi, nitori ọmọ ti nwọn bi ni eşi ẹsẹ rẹ nwọ 'lẹ gẹrẹgẹrẹ ẹru yẹn lo si mba wa lọtẹ yi, lo fi mu wa ṣe adura fun wọn boya ọkan won yio rọ nitotọ gẹgẹbi adura wa.

Ohun ti o wa ko arẹ ba enia fun ọdun na ni wipe titi ọdun fi wọ 'mu to bapi okiki rẹ ko murọ to bi o ti ni lati ri, nitotọ ni nwọn npa lowe pe bi inu ilu ko ba dun bi igbẹ lo nri, ekini ọwọ pọ ni ilu tobẹ ti a ko gbọdọ wi nkan miran, bẹni aisan ati iku mbẹ to, gbogbo mẹtẹta yi na ko to ohun ti o le ko arẹ ọkan ba ẹlomiran, boya o mbẹ ninu ọpọlọpọ enia nisisiyi ti o mbẹ Ọlọrun lati bo on ni aşiri owo ti on yio ri na ninu ọdun na, bẹ nwọn pa lowe pe owo ko si enia ko suwọn, Ọlọrun ko bo gbogbo wa ni aşiri de lẹ, ọdun 1928, yi ko si bi o ti jẹ ni, ọdun 1997, ni a tilẹ nwi pe o le diẹ, a ṣe ọsan ni yẹn kẹ si tun jẹ ki Ọlọrun ma tunbọ ṣanu fun wa kẹ—amin.

A ki gbogbo nyin patapata ẹ ku ipamọ ọdun na, Oluwa ki o ma ṣai fi ọpọlọpọ rẹ han wa, Oluwa ki o maṣai ṣe ọdun na ni ọdun ọsan fun wa; aşẹ—amin.

### A TOTO O, ARERE!

A fi eyi kede fun ẹnyin ọkawe wa pe ti o ba di ni ọsẹ to mbọ logo Ọlọrun ni a o bẹrẹsi ṣe awọn akojọ ohun pataki ti o ṣẹlẹ larin odun (1928) gẹgẹbi a ti ṣe sinnu iwe-irohin *Eko Akete* ti ọjọ keje oşu January to kọja fun ti ọdun 1927, ohun ti o mbẹ nibẹ lọtẹ yi ni wipe a ko ni le pari iṣẹ ti o mbẹ ninu rẹ lẹkan, nitorina a o bọrẹ ninu iwe ti ọsẹ to mbọ 29 oşu yi, a o si pari rẹ ni ọsẹ ti ọdun titun 5 January 1929.

Ki ẹnyin okawe wa mura daradara lati toju iwe ọsẹ mejeji na s' ọwọ daradara fun iranti ẹhin ọla.

### ABỌ O!

A fi eyi ki Ọgbẹni Lẹya Isaac Kuşika Robert ẹniti o ti lọ si ọna ilu Warriy lati bi ọjọ mẹta ti a si gbọ wipe o ti padade ni ọjọ *Monday* ijẹta.

### PANTIWA?

A şe akiyesi omi-ilo ti o mbẹ ni Scott Street, pe o ti duro fun lilo lati bi ọjọ mẹta—pantiwa. ?

### ẸJUGBAGBE!

Nigbati a ro orukọ ti a ba sọ wosika, awọn ohun ti o şẹlẹ larin ọdun yi eyiti a sọ wipe a o bẹrẹ ni şişe ninu iwe irohin yi lati ọsẹ to mbọ, kọ si orukọ ti o yẹ ti a le lo fun wosika na bikoşẹ orukọ ti a fi si oke yi " Ejugbagbe."

---

Ọrọ wa ọsẹ yi on ni nipa ọrọ owo ni ode Eko loni, lati ẹnu bi ọsẹ melo sẹhin ọpọlọpọ gbanjo ọja lo nşe tirẹ ni ilu ọpọlọpọ enia ko ni mọ ki lo ba sababi yi wa, wọn aşe bi inu ọlọja lo dun tobẹ, şugbọn to ba wa idi rẹ, wa ri wipe ọpọlọpọ ọja titun lode lati ẹnu bi oşu meji sẹhin sibẹsibẹ ti lailai lo joko rẹkẹtẹ yi, ewo l'oluwa rẹ ma şe si, ko ju wipe ka ko ti lailai ka ko da sode ka lu ni gbanjo ki owo le wọle lati fi ra ọja titun, ero yi dara pupọ, bi ko si bẹ, awọn ọlọja yio ma yọnu wipe ki lo şe, to wa gba ọja rẹ, awọn Banki wọn a ranşẹ wipe ewo lewo nipa owo to ni lati san, lati bi oşn kan sẹhin, nipa eyi awa ko da awọn to nta gbanjo ni ẹbi, nitori nkan ti a ti fi nda ara wa ni ẹkọ nipe, bi Cocoa ba dide ọja yio ta şugbọn Cocoa dide na, ọja losun yi ewo ni orin ti a ma kọ si yẹn aya fi gbanjo tita, lo ma tan ọrọ owo ni Eko yi lode oni. Gbogbo ọna ti ero ngba wọ ilu, gbogbo rẹ ni awọn oyinbo onişowo şi şabu si, nipa bẹ awọn ara ilu okere papa ko fẹ wa si Eko mọ, aya fi awọn to ba fẹ Eko lati mọ, to jẹ wipe wọn ko wa si Eko ri, nitori na ninu ọdun to npari lọ yi, adura wa nipe ki Ọbangiji şina owo dara-dara fun wa ni ọdun titun ti a ma bọ si titi ọsẹ meji loni, ka şowo ka jere ka ni owo rere lọwọ.

### IBA FUN MUNISIBA ONILERA ILU.

Gbogbo ẹyin ọkawe irohin mi ọsọsẹ ni yio ya lẹnu wipe kini mo ma ri sọ ninu ọsẹ yi nipa Munisiba ninu eyiti ọdun Keresimesi nbọ yi ti gbogbo enia npa ilẹ ọdun mọ; şugbọn nigbati enia ba kọja ni ipẹkun adugbo ti amọ ni Ọbadina Street lọ si apakan Carenna lọ si waju Tokunboh ni apakan yio şe akiyesi wipe kosi Gọta nibẹ ti awọn aladugbo wọn yi le da omi si, tabi irufẹ adugbo bi ologun ọpọlọpọ enia yio sọ pe awọn enia wọnyi ki san owo itunluşe ni? Tabi kilo şe ti gọta ko si ni agbegbe rẹ, bẹni awọn enia wa wọn nmu enia to ba da omi rirun si ita yala ni ẹhin agogo mẹwa tabi agogo marun arọ fẹrẹ ki ilẹ mọ bẹni awọn ẹni wọnyi bi wọn de omi na mọ ile, awọn wolewole wọn a sọ wipe ka si nkan ti omi lilo fi di tanwiji bẹni nigbati wọn ba da omi yi si ita gbangba yi di wipe Ọlọpa nmu wọn bẹni awọn wọnyi won san owo itun ilu şe fun ijọba Munisiba, mo fẹ ki awọn olotu Munisiba ri si awọn adugbo wonyi, ki won si şe Gọta fun wọn, ki wọn ma ba ri aseko yi ano, ki omi rirun ma di on ti wọn nmu wọn lọ fun Baba ẹgbẹ si, ki okun agbo ko ma di ori iwo, awa ko fẹ lati tako ijọba Munisiba şugbọn a fẹ ki ijọba Munisiba ki wọn fi eti si on ti aba sọ, ki wọn ma fi da agunla, nitoto ani awọn aşoju wa nibẹ şugbọn a ko le gun le awọn wọn yẹn ki wọn ma di wa lona ati ma sọ on ti aba ri. Abọ wa re o. Ki Ijọba munisiba ko pẹ o.

### OŞU AWỌN ALAPARỌ NPARI LỌ.

Gẹgẹ bi ati nso ọrọ nipa awọn alaparọ, ati awọn ako ti won wa ba tẹni wọn yi to, şugbọn sibẹsibẹ bi ati nge wọn lọwọ ni won nbọ oruka, nipa eyi ti a nwi yi ki şe wipe afi nşọ ọrọ ai ri nkan sọ şugbọn a nfi nhan yin bi iwa agbere ti pọ ni eko to ni ọrọ ti a nsọ nitori pe on ti a nri nipa awọn ọmọ wa, a ko ro irufẹ bẹ si wọn rara, ẹnikẹni to ba nwọ Reluwe ni ọjọ ijọ ọsẹ ni yio ri wipe awọn panşakuta wọnyi, won nwọ ọkọ lọ titi lọ de Abẹokuta la lai mọ ibi ti wọn nlo, bo ya ni Teshan kan won a jẹ ri ojulumọ ti won ma parọ gẹgẹ bi ake ti wọn gbe lọwọ lati fi ke ẹnikẹni ti eşu ba tari si won, şugbọn bẹni eşu lo nba ahun nọ owo rẹ, awọn mi wa ninu okunrin ti won ko le fẹ oju fun iya wọn to jẹ wipe bi won ba ti leri ikan ninu awọn alakọri wọnyi ohun to nşe wọn tan ni abẹ ọrun, odi wipe ki wọn ma gbọ ti Baba ati Iya wọn mọ, kilo ti ẹ fẹ ki won gbọ ti awọn obi wọn fun? Şe eşu ti yan Iya ati Baba fun wọn şe iyẹn na to gbe jo, gbogbo dukia ti Ọlọrun pilẹ fun wọn odi nina lori nkan buruku yi omiran to jẹ wipe obinrin panşaga ti eşu jaja tari si, odi wipe ko ma bọ, bi ẹnikẹni sọfun wipe iyawo to npọn to ngẹ yi, oti lọ si ọdọ awọn "*Kobokobo*" odi wipe ki ọkọ yẹn ma so fun iyawo ayon to npọn nitori boya o pupọ fẹrẹ wipe lagbaja sọ wipe o nlọ si ọdọ Mista "So so and so" on papa yio sọ pe on, ki lo ni lọwọ ti on mọ wo, elo lo ngba loşu ti on ma fi jẹ ohẹn fun yin, iro ni ẹlẹgiri npa ti oma fi lẹ pẹrẹn yio sọ fun ẹniti to wi yẹn wipe iwọ ko gba on ti arale mi nsi, wipe iwọ nba mi ni ọrọ, iyẹn papa yio sọ wipe bi emi ko gbọ işẹ di şişe ni yẹn, on ti mi o ba şe ti won ba nro simii yẹn ni ma şe alakori yi gbagbe wipe on to ba wa ni ero ẹni ni şişe ni enia ma nşe, awodi to nre ibara ori on to şi nidi on iyen di şişe niyẹn! ọpọlọpọ awọn nkan buruku yi ni nşigbo lọ kakiri wipe ewo le wo, ọdun nbọ, iwo şa lahun bẹni okọnju wa enia lo nmo wipe enia lahun, omiran yio sọ wipe owa ni şabu ko le jẹ anfani rẹ, ewo ni alakọri jẹ ni ọdọ ọkọ rẹ aro! Omiran yio sọ wipe ẹyin ọmọde şoro ba ti yo bo ba gba

ọjẹgẹ ayo tita fun panṣaga alagba ni Sobia da ọ, Gbogbo awọn wọnyi, wọn ko wa ika kan lati arọ wọn wa nwa ni ọdọ rẹ ni eyiti ọdun nbọ yi! bo ba gba pẹrẹn Sikiọriti rẹ ni iwọ nfi ṣere yẹn, wọn o da ẹ kalẹ, to jẹ wipe igi aja lo ma ka, eyi ti iwọ ṣẹṣẹ ngbe lọ si ọdọ Dokita ore melo lo ṣe ọkọ rẹ arọ to wa jẹ wipe ọdọ rẹ lo wa ma so oṣuka rẹ si? Eyi ti iwọ oro ko to ọ, iwọ gbagbe ọmọlọmọ to gbe si ọdọ to nṣe ọlọjọjọ rẹ, ni ijọ mimu tabi ijọ jijẹ, uijọ ai ri jẹ, tọju iyawo rẹ Ọlọrun yio pese ni ọdun to nbọ yi ma gbọkanle awọn alaparọ wọn yi o.

### KERESIMESI ỌDUN DE

Ni ijọ mẹrin loni, ni ao bọ si ijọ ọdun Keresimesi ti ọdun 1928. Bawo ni iwọ ti fẹ lo ọdun na si, iwọ fẹ lati fi ọdun yi ṣe ọdun ọmuti ni? Tabi iwọ fẹ lati joko ko maje ko ma mu, ko ma ro ọdun to kọja lọ bi irufẹ ipo to wa nigbana, tabi iwọ ko ni ro bi ọdun 1929 ti ma ri fun ọ, bi iwọ ti ṣe ma ri iṣẹ ṣe, bi iwọ ti ṣe ma ri owo ṣe, bi Ọlọrun ti ṣe ma bo ẹ ni aṣiri ati ri iwe ile rẹ gba pada, bi iwọ ti ṣe ma san gbese ọrun rẹ, bi Ọlọrun ti ṣe ma ṣe ayipada anfani fun ọ fun rere, bi Ọlọrun ti ṣe ma fun ọ ni ika kan ni ọdun to nbọ, bi Ọlọrun ti ṣe ma ṣe iranti anfani fun ọ. Nitori na jọwọ ronu jinlẹ ni Keresimesi yi ki iṣẹ ma duro fun ọ, ma fi ọdun yọ iyọ ayọju ti akere ṣe fi itan ṣe.

Ni ọla Sunday ijo kẹtalelogun oṣu yi ani reti wipe ọkọ ogun Australian ti a npe ni "Canberra" yio bẹ ilẹ yi wo, ọgagun ọkọ na ni G. L. Massey, a ri eyi ka ninu iwe irohin Daily Times ti 19th December 1928. Nitori na ẹyin enia wa, ẹ o ni fi onjẹ oju fun oju, lati lọ ganni ọkọ yi bi? Ao si ni reti pe yio yan afọnja fun wa ni alẹ ọjọ aisun ọdun ni ọjọ Monday 24th.

### ORI ERE NI ẸṢIN KU SI.

Loni ni ọjọ Saturday, ni agogo mẹta kọja iṣẹju mẹdogun ni ere ẹṣin ti ọdun Keresimesi wa ni ọdan gẹgẹ bi wọn ti nṣe, ẹ lọ fi onjẹ oju fun oju.

Emi ni ti nyin nitotọ.

ENIA KO DA BI ALLAH.

---

ORI V.

## IGBOIYA.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KẸRIN.

Otọ ni a ri ọpọlọpọ awọn enia nla ti aiya wọn a duro gbagba ti wọn nigbati iyọnu ba de ba wọn, ṣugbọn ti Moore ko ri bẹ. Nigbati o nbẹ ninu tubu ni Ile-Iṣọ giga, obirin rẹ ko tu ninu pa-pa. O ro pe ẹjọ ara rẹ ni ti a ko da a silẹ, nitoripe bi o ba ti jẹ ọhẹn si eyiti Ọba nfẹ lọgan ni nwọn yio da a silẹ ti yio si pada si ile rẹ mere-mere ni Chelsea, ti yio lọ gbadun awọn iwe rẹ, Ọgba eso rẹ, ati Obirin ati awọn ọmọ rẹ.

Ni ọjọ kan obirin rẹ sọ fun pe: "Ẹnu ya mi lati ri i pe, iwọ ti a ti npe ni ọlọgbọn wa nhuwa omugọ iru eyi; "o joko tẹtẹrẹ sinu tubu jatijati o ba awọn ekute mule po, bẹni bi o ba gbọjẹgẹ ti o ṣe bi awọn Bishop ti ṣe ni, o ba ti di ominira ara rẹ." Ṣugbọn ọna ti Moore ro o si otọ ni; loju rẹ ọran yi ki iṣe ọran ara rẹ; gbogbo aroye ti obirin rẹ si ṣe ko wọ ọ leti. O rọra pa ti obirin rẹ ti Sa-pakan, o fi ẹrin da a lohun, o ni:—

"Lati ile yi si ọrun, ati lati ile mi si ọrun, ọkan na kọ-bi? Nwọn ko jina ju ara wọn lọ."

Obirin rẹ wo o tika-tẹgbin o ni "Yẹyẹ idi igba-yẹyẹ ra!"

Ṣugbọn ọmọ Moore Obirin, Margaret Roper, ki baba rẹ lọkan ki o duro dede lori ipinu rẹ, o ntu ninu, o nse ajo rẹ nigbati o mbe ninu tubu ki o ma ba kọwe, nwọn ko jẹ ki o ri gege ati omi-iwe, ṣugbọn o fi ege edu kọwe si ọmọ rẹ. Ninu ekan ninu awọn iwe wọnyi ni o sọpe: "Bi emi ba ni ki nkọ ọ silẹ ninu iwe bi igbadun ti awọn iwe ti o nkọ si mi ti to, agba edu kan ko to ṣe gege" Moore ku sidi otitọ: o kọ lati bura eke; a si pa a nitori o kọ lati ṣe madaru. Nigbati nwọn gbe ori rẹ, nwọn fi kọ si *London Bridge* gẹgẹ bi aṣa oju dudu igba na. Margaret Roper gboju gbaiya o tọrọ ori na; ifẹ ti o ni fun baba rẹ ki ṣe igbati on papa mbẹ laye nikan ni, nitori o ni o fẹ ki nwọn sin ori na pẹlu on nigbati on ba ku: lọjọ gbọrọ lẹhin eyi nigbati nwọn ṣi orori Margaret nwọn ba ohun iranti pataki yi lakaiyr rẹ, on na papa ti di eru.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-OSA

KERE O!

OYINBO KESSLER GBE TANÀ DANU, O GBE MI DE.

Irin-işẹ Gbẹna-gbẹna to dara ju ti nwọn ti nlo fun iwọn adọta ọdun sẹhin wa fun tita ni Şọbu Kessler.







Ẹ ba mi lo si Şabu na, ẹ o ri ti nyin yan nibẹ, ọpọkupọyọku ni owo rẹ, iba diẹ ni o wa. Aworan Irin-işẹ wọnyi ni a ya sinu iwe yi fun nyin yi. Lọgan lẹ o ri ra.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjo Lane, ni Eko.







Ẹnyin ara Eko,, ara Oke ati ilu miran, gbangba dẹkun, kedere bẹwo, Şabu Kessler ti kuro ni mori nkan firi irohin ko to afojuba. Ẹ ma şe gbẹhin ki ẹ to a ti nyin, ki ẹ ma ba joku Ologbo.


Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ foji o.

Iwe-irohin, ohun iyebiye ni, Atọnisọna ni, Amọna ni, nitori eyi a bẹ awọn Alagbara wa pe, nigbakugba ti a ba ba wọn sọrọ ninu Iwe-irohin, ki wọn ma fi ọro wa si ero ijinlẹ, ki wọn si ma şe eyiti o tọ. Oluwa yio si ran wọn lọwọ. Ninu Iwe-irohin "Eko-Igbẹhin" ekini ni Ọdun kẹta ọpọlọpọ ọrọ la fi han nigbana şugbọn ẹhin igba la yin agbado si, ọkan ninu ọrọ wa igbana la tun mu wa si iranti ẹyin Ọkawe wa.

Ni 1877 ni ina Hotọnu jo, şiwaju ina Hotọnu gbogbo ọja Ọbun Eko jẹ Buka awọn to nta Ẹja, Ata, Obi ati oniruru nkan jijẹ, lakoko na ni Ologbe Jeremiah Cole şi Shop Provisions si Ọbun Eko nibiti a gbe fi ko Ile Isin Ọlọrun Ijọ Wesleyan ni Ọbun Eko loni lakoko na a ko şe alaini Atunluşe işẹ Atunluşe ni Ologbe Daddy Glosefer şe, işẹ atunluşe ni Ologbe Daddy Parlomiras şe, bi buka kan ba gbo wọn a sọ fun oni buka ko tun kọ, bi omi ba rogun tabi bi koto ba wa ni ẹgbẹ Ile Ọlọrun Ọbun Eko nigbana (Shabu) Shop, wọn a paşẹ pe ka tunşe, tabi bi ilẹ ba dirty wọn a paşẹ pe ka gba, işẹ atunluşe igbana ko ju wọnyi lọ.

Ni January 1878 ilẹ gbigbona kan ja, (Small Pox) l'eko yi işan ilẹ gbigbona yi lo gba ọpọlọpọ awọn Baba wa lọ awọn Oloruko giga, Oluwa ko dẹlẹ fun won, Amin, lẹhin Iku wọn a ko tun gbọ pe enia kan tun ku ninu ile wọn fun ọdun pupọ, bẹni a ko ngbe oku nigbana a ko si nko awọn olugbe ile lọ pamọ si ibomiran nigbana, şugbon loni bi enia kan ba ku ninu ile kan bo ba ti jẹ pe Shanpanna lo pa, oku na di gbigbe awọn olugbe ile na di kiko lọ pamọ si ibikan ti nwọn npe ni Korọnti, ani ọmọ ko tun mọ orori Baba ẹ, Ọkọ ko mo ibi ti a sin oku Aya, Aburo ko ri ati snn ẹgbon ẹ, eyi nkọ o, emo nla ha kọ ni iwonyi? Bi ọrẹ ba gbo pe ọfọ şẹ ni ile ọrẹ on bo ba lọ, a ko dẹ ni fi oju kan nwọn ọjọ mẹfa tabi jubẹlọ boya nkan pataki kan lo nşe jọwọ to fi sure lọ, a ko fẹ mọ, mo tun bere, emọ nla ha kọ leyi? Ẹyin ọkawe wa, ẹnikan lọ si ogun, o pa mẹfa nigbati ode ile o rohin fun ara ile pe on pa mẹfa wọn ni ha ha ha, oni o dara o gbe ayo silẹ o tun pa mẹfa, o ni bi ti ogun ko şe oju yin ti ile nkọ? Toto, bi ti January 1878 adota ọdun ba lọ ni iranti ẹyin ọkawe wa, mo bere ti Ayọkẹlẹ ijẹta yi nkọ? Oluwa ma jẹ ka ri iru ẹ mọ, Amin, a ko ma ngbe oku nigbana, bẹni a ko si ko awọn to ngbe ile na lọ si ibikibi sibẹ sibẹ Ọlọrun ko ha şanu wa bi? Ni 1887 ọdun kọkanlelogoji ẹ ranti pe ojo kan bẹrẹ si rọ ni ibẹrẹ oşu ko fi işẹju marun duro ko to tun bẹrẹ şugbọn nigbati eyi nlo bi ogunjọ ọjọ tabi ọjọ mẹdogbọn, şe on ni Gomina wa igbana mo ro pe Sir Alfred Moloney ni, o ranşẹ pe Ọba wa Oyekan o si sọ fun pe ko jọwọ ko ba on şe etutu si ilu ẹ, nigbati o han gbangba pe

omiran fẹ wọ, Ọba wa ṣe etutu Ọlọrun gbọ, Ọlọrun dariji, ẹ tun ranti, ni igba ayọkẹlẹ, nigbati ilẹkun Ile Ọlọrun ti, ko ha ṣe pe etutu lo gba gbogbo ode Eko wa kan, nigbati ajakalẹ arun tabi aluba ba wo ilu kan etutu ni wọn nṣe si ilu, a ngbe oku, a nko ni kiri emi ko ro pe oran ohun ti nba wa ja o.

Ẹ ranti pe aṣẹ Oluwa ni pe, aterigba ki atẹrigba ki atẹrigba ti Angẹli apanirun ba ri ẹjẹ ko re ibẹ koja, etutu ki ṣe ohun kekere nitorina a bẹ awọn Aṣoju wa, Ọlọla C. C. Adẹniyi Jones, Ọlọla E. O. Moore ati Ọlọla T. A. Doherty ẹyin la gbẹ ẹru ilu Eko yi le lori, ẹ ba wa fi ọrọ oku gbigbe enia kiko lọ pamọ wonyi siwaju awọn Alaṣẹ wa, ni Ikọle Irun, ati awọn oniruru ile awọn Baba wa loke Shọpanna ma nja nibẹ won ko ngbe oku Oloku lo nsin oku awon Olusin Shọpanna wọn a si ṣe etutu, awọn ara ile na won ko ma nfi ile na silẹ o, nitorina a tun bẹ ẹyin Ọlọla wa ẹ ba wa mu oju to ọrọ yi. Oluwa yio si ma ran yin lọwọ. Amin.

Emi ni,

KOṢẸHIN ỌLỌRUN.

---

USE OF OBSCENE LANGUAGE IN THE STREET.

Fọlawiwọ ( Female, ) 55, was bound over to keep the peace for six months by the Police Magistrate, Lagos, yesterday, having been found guilty of using obscene and abusive language at Taiwo Street.

The accused was first brought to court sometime ago but she was then remanded in custody for medical examination. As a result the Medical Officer issued a certificate declaring that she was sane.

One of the witnesses for the prosecution was Mr. E. J. Alex Taylor, Legal Practitioner, who stated that he saw the accused abusing another woman named Flora Cole and using such filthy language as he ( witness ) could not repeat in court. The Magistrate gave the witness a piece of paper to write down the words used ; which he did.

In passing sentence on the accused the Magistrate said that he took her age into consideration but any time she is brought up again for such an offence she would be sent to prison. *The Nigerian Daily Times* ; *15/12/28*

We made to understand that madam Fọlawiwọ is the mother of Mr. Christopher Babatunde Williams of Audit Government Department, Lagos, and of Taiwo Street, Lagos.

Madam Fọlawiwọ is a staunch member of Seraphim and Cherubim.

PAGIDARI.

## ỌMỌ NI O JOGUN.

Ẹbun ọmọ jẹ ohun ti olukuluku ẹda nwoga si lati iṣẹdilẹ aiye. O jẹ ipari gbogbo ẹbun ti o wa laiye yi, pe lẹhin ẹbun yi ko tun si eyiti o tobi ju u lọ mọ, tabi ti o niyi to o mọ, Ọmọ, ibẹ lo mọ, ipari ẹbun. Awọn omiran ode miran ro pe awa enia dudu fẹran ọmọ pupọ, pe bi a ko ba bimọ, a ma dun wa. Eyi kiṣe aniyan awa enia dudu nikan rara. Ife lati bimọ jẹ itẹle aṣẹ Ọlọrun, Ẹniti O sọ pe ki a ma bi si i, ki a ma rẹ si, O tilẹ tun wipe ki a ma gbiyin l' ori ilẹ ( ṣugbọn ko sọ pe ki a ma bi ibi aiwo ti eranko ) lati inu Majẹmu lailai, aniyan lati bimọ jẹ ero ti o ga julọ ninu awọn ara igbani, titi fi de inu Majẹmu Titun. Ọran ẹdun Abraham ni pe ki on le bimọ bayi, Rachel tilẹ ja tirẹ ni ija ajahun gbangba, a ko ri ẹbun ti a le bun obinrin ara Ṣunemu, nitoripe o ri jẹ, o rọ o lọrun, ṣugbọn nitoripe ko bi, a bun l' ọmọ. Hannah, aya Elkanah ba Ọlọrun jijakadi pẹlu aisimi ninu adura aisimi, Ọba na si re ẹ l' ẹ un. Sakaria, ninu adura aisimi, o tọrọ ọmọ, adura rẹ si gba. Apẹrẹ wonyi to lati fihan pe ifẹ lati ni ọmọ ki nṣe arun ara awọn enia dudu nikan, bẹ kaiye ni a le pe e.

Eyiti o pamọ fun awa ẹda nigba miran ni pe, a ki ranti rara pe ẹbun ni ọmọ jẹ, ẹbun ni owo, ọgbọn, bibini rere, ẹwa, ati awọn ẹbun yoku, ẹniti tabi ẹlomiran ti a ba si kojusi ṣe lore lati ni owo ati ọmọ, tabi ọmọ ati ọgbọn, awọn bẹ a ma ṣiro pe ọgbọn inu wọn ni, mimọṣe wọn ni, iṣina nla ni eyi.

Ṣaṣa agbo ile ni a gbe nri ti owo ati ọmọ jo npọ, ko ṣe pe ko wa, ṣugbọn ko pọ rara ni. awọn ti a ba si ṣore nla bayi fun a ma foju tinrin awọn ti ko ri bi awọn ti ri. O ma buru o ! Owo ko to fi ṣe igberaga si enia, nitoripe o le gunyẹ lọla a si fo lọ. Ọmọ ko to fi ṣe labilabijọri, nitoripe ọpọ ọmọ ti a ro pe nwon bọ lọwọ iku, nwon a si fo ṣanlẹ, nwọn a ku, agbosogbanu ni iku wonyi si jẹ fun gbogbo enia. Nitorina olowo ni o, o bimọ ni, o ni ẹwa tabi ọgbọn, maṣe fi ṣe igberaga tabi fọrifọri, ki Ẹṣu ma ba fi o sun Olodumare.

*Eṣe ti ọpọlọpọ enia ki bimọ ?* Ibere na le pupọ, a fẹrẹ ma mọ bi a o ti dahun rẹ pelu. Lọna kini, aibimọ awọn ẹlomiran le jẹ pe Ọlọrun ni ko fun won, boya rara, tabi ko tete fun wọn.

Ṣe o pẹ Abraham bẹ ? bẹ na ni o pẹ Sakaria, Ọlọrun sa se inu Rakeli fun sa kan, ko ṣẹhin Ọlọrun ṣa. Lọna keji, boya o le jẹ pe arun pataki kan ndi ọkọ tabi aya lowo, a ki mọ o le jẹ aiso gbe jẹ m' ọwọ ọkan tabi ekeji, nwọn a ti ipa bẹ ṣẹ ebu ti ko wọ. Lọna kẹta, bi Ọlọrun ba ri wipe ko ni ṣanfani fun wọn ki pin fun wọn. Ki Edumare ma jẹki a bi ọmọkọmọ ; idi re ti awọn miran fi nkọrin pe " pẹngele, emi ki mo bi were. "

IYALODE

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, DECEMBER 22, 1928.

## AGBA K'AGBA LODE EKO; AWỌN AGBA B' O BA K' O MU B' O BA O BU LẸSẸ.

Pupọ awọn agbalagba ni mbẹ ni ilẹ yi ni ode oni ti iwa irira wọn si awọn ọmọde tabi awọn ọdọ ko ṣe fi ẹnu sọ, bi o si bi wọn lere kilo ṣe sababi ti eyi fi ri bẹ, awawi ni nwon yio ma wa pe Lamọrin gberaga ju, Tamadu ni fari pupọ tabi Lakaṣegbe yaju ju, ti o ba si wa idi awawi yi daradara iwọ yio ri pe ọrọ ko ri bẹ rara: o di agbalagba melo ni awọn ọdọ le sunmọ pe ki nwọn ṣe iranwọ kan fun wọn ti nwọn yio si fi tayọtayọ ṣe? Bi ọdọ kan jaja lọ si ọdọ alagba kan pe ki o jọwọ ki o ma ṣai ṣe iranwọ owo diẹ fun on nipa owo-yiya ti ọdọ na ko ba si mu nkan iduro ti o jọju loju alagba na lọ si ọdọ rẹ, oṣe ni agbalagba yio ma pa ti yio si ma fi ọwọ lu ọwọ pe "Ọja ko ta" "Ode ko jẹun" ati irufẹ ọrọ bayi; ṣugbọn agba na mura tan lati ṣe inawo ni ọna miran ni ọna aṣehan: agba miran kọ lo si mbẹ ti adura gbigba rẹ fẹrẹ le mu ki ọrun wo ṣugbọn ti iwa rẹ si ẹda ẹlẹgbẹ rẹ ko jẹ iwa eyiti awọn ti a tilẹ npe ni keferi le hu si ọmọ-enia agba miran nwa tan lati ṣe keta ọdọ miran lẹnu iṣẹ rẹ. Bi o ti wa larin awọn agba ọkọnrin bẹ si ni o wa larin awọn agba obinrin, ni koipẹ yi kọ ni a gbọ pe ọdọmọbinrin kan tọ agba obinrin kan lọ lati haya ile rẹ ti a sọpe o mbẹ leti ebute kan lati ma gbe fun igba diẹ titi ara ọdọmọbinrin na yio tubọ bọ si ipo lẹhin aisan ti o ti ṣe: kini esi ti a gbọ pe agba obinrin yi fi bikoṣe esi mọnamọna pe alarede *( a marierd person)* ni on fẹ ko haya ile on na ẹnyin mọ kilo kan a gb'Arede a ko gb'Arede pẹlu hihaya ile fun anfani ara ẹni:

Ẹwẹ agba miran si mbẹ ti a gbọ pe ọrọ bi ẹpe bi epe ni mma ba awọn ti nwọn ba wa ya owo lọwọ rẹ sọ: a sọpe bi lamọrin ba wa fi iwe ile ya owo lọwọ rẹ ti o ba si nka owo na fun ọrọ abami pe "Njẹ iwọ a le wa gba iwe rẹ pada bayi" "ko ma daju pe iwọ le ri owo na mu wa mọ o" ni a gbọ pe o ma nsaba jade lẹnu agbalagba yi.

Awọn agba miran ki kọ lati gba ohun ini awọn ti ko to wọn mọ ti wọn, o ti di agba melo ni agbọ pe o ba awọn alairiṣe miran wa iṣẹ tabi ti nwọn da iṣẹ silẹ fun diẹ ninu awọn alairiṣe ode oni? Agba isisiyi ki iṣe agba ti ọdọ kan le sare tọ lọ ni igba idanwo, bẹ bi o ri wọn ni ode iwọ yio wipe laisi aniani awọn Lagbaja to sa tọ ni akoko ti o ba le.

Bi a ti nsọ bayi a dupẹ pe gbogbo awọn agbalagba wọnyi kọ ni wọn ni iwa Agunla lọwọ tan a ri awọn agbalagba bi meji mẹta kan ti nwọn ko fi iranwọ wọn du ọdọ ri. Nitoto ọdọ miran wa ti nwọn jẹ alaimore, ṣugbọn iwa afojukamọ ti agbalagba pupọ ni, lo njẹ on, bẹ a woye pe kosi ẹnikan tabi agba kan ti o ti gun igi ti o si ti ri ẹhin aiye ri.

Ni gasikiya

Ọlọrun j'enia lọ,
Enia!!!

---

## TANI NFẸ A NI.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irọhin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Nigba kan ri ti awa kọkọ ngbọ ede bayi "Tani nfẹ a ni," ko ye wa to daradara nitoripe a koi gbọn daradara debi ti o a fi ni lakayi eyiti a o ma fi ro ọrọ nigba na, a ṣebi nwọn nsọ wipe tani ẹniti o nfẹ awọn ni.

A ko mọ wipe ede na mbi ni lere ni pe tani nfẹ ki a ni, nitoripe nigbati emi nro gẹgẹbi ọgbọn omugọ temi, mo fẹrẹ le bere wipe ki ni nwọn nfẹ fi ta ọrẹ lati ọjọ yi ti nwọn ko ri ẹniti yio gba nkan na lọwọ wọn, ati pẹlu ẹnikan fi gbolohun ọrọ na fi njẹ oriki nigba kan ni ilẹ yi, diẹ lo ku mo fẹrẹ le tọ oluwarẹ lọ pe ohun ti o nfẹ fi ta ọrẹ na ko bun mi ninu rẹ, ọran ẹrin kọ o.

Nigbati ọrọ na wa ye wa dajudaju ijinlẹ ọrọ ni fun ẹniti o ba mọ gbogbo ọro.

Tani ọrọ yi wa mbawi julọ loni, o mba opọlọpọ enia wi, o mba tẹgbọn-taburo omiran wi, o mba obinrin meji omiran ti nwọn jẹ orogun tabi aya ọkọ kanna wi, o mba awọn ọrẹ meji omiran wi, o tun mba awọn Ọbakan miran wi, ni alaye awọn ẹniti ile wọn fi ẹgbẹ kan ara wọn ni o njẹ alamulegbe, tani ẹniti o tun mbawi, o mba Ọga iṣẹ meji omiran wi.

Afi tani ẹniti ko bawi julo ni waliya loju wa, ko ba tọkọ-taya wi, ẹwẹ, ko si ba tun baba-tọmọ tabi iya-tọmọ wi.

Bi o ti wu ki o ri, ọkọ kan kò jẹ fẹ nkan buburu fun aya rẹ, bẹni aya kan ko jẹ fẹ nkan ti ko sunwon fun ọkọ rẹ bikoṣe ti nwon ba fẹ da 'ju ara wọn loku, bi o ba si ṣẹ ndogun wipe tọkọ-taya tabi ti obinrin kan nfẹ nkan buburu fun ọkọ rẹ nkan omiran fẹ wọ ọ ni iyẹn, a jẹ wipe nwọn ṣẹ nmura lati pin gari ni.

Nipa ti baba pẹlu ọmọ rẹ, a kole gbe ogun nyẹn leri tobẹ, wipe ọmọ omiran kole fẹ ohun buburu fun baba rẹ, kini irufẹ ohun buburu bẹ, ti o ba jẹ wipe baba na ni dukiaya lowọ daradara, ọmọ ọlọkanjuwa omiran le ma ṣadura pe ki baba na tete lọ, ki awọn dukiya rẹ gbogbo le jẹ ti on, sibẹ-sibẹ ẹdaju ati ole ni a le pe ọmọ bẹ.

Ṣugbọn bi ko ba di gbangbarigida tan wipe ọmọ omiran nṣe opọlọpọ laifia si baba rẹ, baba na ko jẹ gbero buburu si i amọ nipa iwa buburu gbogbo ti ọmọ le ma hu si baba rẹ a kole ri iyan ja si ori rẹ.

Eyiti a mọ ni pataki julọ ni wipe ohun iṣoro ni fun ọmọ kan lati wa ohun aidara pẹlu iya rẹ, nkan ki nkan ti iya na le ni lọwọ ọmọ na ni lati ma ro ọjọ meji fun iya rẹ, ọjọ wo? Ekini o ni lati ma ro odidi oṣu mẹsan onka ṣi ikẹwa ti iya rẹ fi ru oyun rẹ, ekeji o si ni lati ma ro ọjọ ti iya rẹ mbẹ ni ori ikunlẹ, nipa eyi ni a ko fi le ri ọmọ ti yio wo ṣunṣun ti yio dide pe on nfẹ ibi fẹ iya on.

Bẹna si ni a kole ri iya ti yio dide ti yio sọ wipe o ngbero aidara si ọmọ on, ohunkohun ti ọmọ na le ma hun ni iwa fun un, iya ni lati ma ro ẹhin ki o ma fi ṣe osun ki o ma fi para aiyafia iya omiran ti o ba gba ibọdi lo ya ku.

Ọna mẹta pataki ti a mọ ni iyẹn, ṣugbọn iyoku yẹyẹ ni fun awọn ẹlomiran, nwọn ko mọ ọ si nkankan loju wọn, ki Ọlọrun maṣe jẹki a lugbadi iru awọn ẹni bẹ.

Ni ode ti a wa yi ẹniti o fẹ ki a ni ko wọpọ, ẹniti ko fẹ lo pọju.

Ṣugbọn a le mọ ede na si oriṣi meji, a le mọ si wipe tani nfẹ ki a ni ohun rere a si le mọ si tani nfẹ ki a ni ohun buburu, dajudaju mejeji ni lati tẹwọn ju ara wọn lọ ohun ti gbogbo wa mọ ni eyi.

Bi ọmọ iya omiran meji ba wa bi nwọn nta kanrangba si ara wọn bayi, a o ṣebi ẹnipe ki iṣe inu iya kanna ni nwọn ti jade, nibẹ si ni awọn Ọbakan omiran yio wa, ti nwọn yio si fi ọwọ mu ara wọn bi-ẹnipe ọmọ inu iya kanna ni nwọn nṣe, a ko tun le ṣẹṣẹ sọ ti awọn Ọbakan omiran ti nwọn o ni fẹ ki nwọn ri imi ara wọn ni Atitan, iwa ti ọmọ inu iya kanna omiran pẹlu ti Ọbakan omiran o fẹrẹ le ba ara wọn dọgba ni aiye ti a wa yi, nitori kini ko ni se lori agada tabi dukiya ti baba wọn yio ni lọwọ.

Ṣugbọn awọn Obi miran ti ko ni lọwọ, a ki isagba gbọ ija awọn ọmọ wọn, lori kini nwọn tun ma ja fun o? O di wipe ki olukuluku wọn lọ wa iṣẹ ṣe ti yio fi ni tirẹ.

Nipa ti obirin meji tabi aya ọkọ kanna, ọna pupọ ni awọn yẹn ko fi le fẹran ara wọn fi nwọn yio si ma fẹ ara wọn pẹlu ibi eyiti a kole ma sọ, o nye rẹ, o nye rẹ ni ikun ara rẹ amọn-ṣeni, o nye awọn papa bi a ti nsọ yi.

ki iṣe gbogbo orogun meji li a nwi, awọn eyiti ko mọ ohun ti nwọn nṣe ti nwọn nja lori ọkọ ọlọkọ, ọkọ-oyun-inu ọkọ aṣẹ-idi li a nwi, melo-mele wọn li a o ka loni, ti nwọn ndure kiri ojule Alfa ati ile Oniṣegun ki ọkọ le fẹran on.

Nipa ti awọn ọrẹ mẹji, dajudaju ika ko dọgba, awọn ọrẹ omiran yio wa, ọkan yi ni nkan lọwọ ju ekeji lọ, ṣugbọn ọna ti gbogbo nkan ekeji rẹ yio fi di tirẹ ni yio ma wa, ekeji ko si ni mọ nkan si ikan, yio ma huwa pẹlu rẹ gẹgẹbi ọrẹ, bẹni ọrẹ omiran yio si wa ti o jẹ wipe bi o ba ri nkan buburu ti o mbọ wa ba ekeji rẹ, ko kọ lati ku si idi rẹ, ki ọrẹ rẹ to mọ, ọrẹ ti awa mọ ni pataki ni iyẹn, nitorina ni a tiṣe sọ wipe ọrẹ pe oriṣi meji.

Bẹni o si mbẹ fun awọn Ọga iṣẹ meji omiran pẹlu, ti ọkan ba ngba owo ju ọkan lọ, ko jẹ Epini ni ti ọkan fi tayọ ti ekeji, yio fe ki owo wọn jumọ jẹ iye kanna, ko jẹ ronu ki o mọ wipe boya o ti de ibi iṣẹ na sin on ni tabi wipe iṣẹ wọn dara ju ara wọn lọ.

Nipa ti awọn alamulegbe, awọn ẹlomiran le wa ki nwọn fi ile gbe ara wọn, bokanran ki nwọn mu ara wọn ni ọrẹ irọ ni, bi ọkan ba ṣeṣi lọ ni nkan ju ekeji lọ, tabi ti ọda fẹrẹ nja ròro lara ile ọkan ti ti—ẹnikeji si ṣa bi aro, ko ni jẹ didun inu ekeji rara, yio fẹ ki ti ekeji dabi ti on, nitoripe on koi ti ri ọwọ yọgbe lati ranṣẹ si awọn kunle-kunle pe ki nwọn ba on fi ọda ju ti on na loju.

Nibẹ si ni awọn omiran yio wa ti nwọn a mu ara wọn gẹgẹbi ẹbi, ti o jẹ wipe bi ọkan ba ni nkan iṣe, ekeji yio ba mura gidigidi gẹgẹ bi ti ara rẹ.

Gbogbo irufẹ nkan bawọnni, ni a ro pọ li a fi sọ wipe "Tani nfẹ a ni"? Nitoripe ko wọpọ larin awọn ẹda igba yi, era ko fẹ poroporo de inu ni iwa ti o mbẹ ni ikun awọn ẹlomiran, bi o ni owo

ọran bi oluwarẹ ko tilẹ ni atara agaga, bi oluwarẹ ni aṣọ ni ọwọ diẹ tabi awọn nkan anfani omiran gbogbo o di wipe ki nwọn ma wa iṣubu oluwarẹ kiri, irufẹ awọn ẹni bẹ gbagbe wipe ori ni Oniṣe ẹda ni ayanmọ, bi Ọlọrun ba ti ṣe Kadara olukuluku si bẹni yio ri, ko si ohun ti o nyi pada.

Bi ẹlomiran ṣe adura titi ti o fẹ gan, bi Ọlọrun ti ṣe ebubu rẹ bẹni yio ri, bi ẹlomiran ko tilẹ ṣe arara, bi Ọlọrun ba ti ni ile aiye yio san an daju-daju bẹni yio ri. Kadara Oluwa ki iṣe 'lẹ, ki Oluwa ma ṣai yan ori wa si rere.

A ro wipe o tọ wipe ki awọn ẹniti o nṣe arankan ẹlomiran lọ ronupiwada, nitoripe nibiti a gbe nwo gẹgẹbi ti lagbaja ti ri, bi ti tamẹdo tilọ si, nibẹ ni ọlọjọ ma de, tirẹ ni o ma wo, ki o si ma bẹ Ọlọrun rẹ lorekore pẹlu Ọkan mimọ maṣe ja tanma dajudaju bi o ti wu ki o pẹ yio dahun Ọba Alanu ni.

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

---

## ITAN ỌGBẸNI BISUGA, ỌLỌLA IPẸRU NI IJẸBU-RẸMỌ,

Ni Iranti Ọlọla Ọgbẹni Bisuga ara Ipẹru, dajudaju Mr. Bisuga afinju enia ni, gbajumọ enia ni, ẹniti o ni ogun isuju ni ọwọ ti a fi njagun tabi ti o fi njagun daradara ti nwọn ko fi nri on tikalarẹ ni oju ogun tabi ni oju ija-ogun papa bi awọn ara Ipẹru ma gbe egbogi lọ si arin awọn ọta awọn ogun ara Ibadan, Mr. Bisuga ni wọn ma fi ran ogun rẹ da ni ọ u pupọ, a lọ ni aibẹru, o fi ogun rẹ gba ilu silẹ ni ọwọ awọn ọta ogun ara Ibadan, iṣẹ rere ti o ṣe ni yẹn, gẹgẹ bi itan ti mo gbọ ni ẹnu awọn baba nla wa.

Ija ogun Ogere ati ara Ipẹru, nwọn ni Mr. Bisuga kanna ni o da silẹ ni ọjọ ọja Ipẹru ogun na pa awọn gbajumo olowo ara Ipẹru pupọ o dun awọn ara Ipẹru pupọ tobẹ gẹ ti wọn fi ṣe ileri pe ki won to ta ẹkọ owurọ ni ọla ni awọn ma lọ ko awọn ara Ogere laiki bẹni awọn ara Ogere si mura bakanna ni yẹn. Awọn ara Ijẹbu Rẹmọ wọn ngbọ nigbati o di arin oganjọ bẹni awọn Ọgbẹni Ọlọla Ode Odẹpeju dide gẹgẹbi alatunṣe ti awon Ọgbẹni ti awọn Ijẹbu npe ni Oṣugbo nlọ tabi nki ge mbo wa ni ati ode ati ilu ogboni wọn pẹlu ti wọn si fi wa si Iglobi larin meji Ipẹru ati Ogere ki akuko to kọ nwọn ti de ibẹ awọn ologboni Ode ti nlu ilu ogboni ni ọjọ keji na ti ija ti fẹrẹ awọn ara Ode ko iẹ ki wọn ja ogun mọ rara ; obinrin ni won sọ pe o da ija na silẹ gẹgẹ bi a ti gbọ si nigbati awon ara Ipẹru de ile wọn ni awọn fẹ pa Mr. Bisuga wẹn ni o ko awon afinju, gbajumo ilu lọ pa si ogun airo tẹlẹ ni ọsan gangan, nwọn sọ fun Ọba Odoru Ọbaṣibọnoye ni alẹ bẹni ọba Ọbaṣibọnoye ko fẹ ki wọn pa rara bẹni o ranṣẹ lọ pe Mr. Bisuga pe ki o ba de ọdọ on o ni bi awon agbagba ba pe tan o ni bi on ba d de ko da ọgbon inu rẹ o, o nwọn nfẹ pa ni, o ni bẹni agbara on ko le gba silẹ nigbati wọn ba ki mọlẹ lati pa ; o ni ọgbọn bi yio ti ṣe ma salọ ni ki o ṣe bi on kuku ti ndide ni oju rẹ nlọ wọ yara on o ni nitori oju on ko ni gba nigbati wọn ba ma tẹ ife ara wọn ni ọtun rara o, nigbati odi ọjọ keji kiakia ẹsẹ awọn ara Ipẹru ti pe jọ si ile oba Ọlọla Ọbaṣibọnoye bẹni Mr. Bisuga joko ti ẹsẹ Ọba lati dimu bi wọn ti ma ki on mọlẹ ni ojiji giri giri ki Ọba ti kọ dide nlọ wole bẹni Mr. Bisuga ti dide ti o si sare lati dure wọ inu yara Ọba lọ ti o da ologbo dudu ti o salọ awọn ti o duro si ẹhinkule Ọba ninu wọn ri ologbo dudu ti o sare jade ninu ile ṣugbọn wọn ko ri enia nigbati wọn bere ni ọwọ wọn ni wọn sọ bẹ, nwọn ni kini ṣe ti ẹnyin ko pa ologbo na Ishoya ni wọn de ti gbe gburo Mr. Bisuga lẹhinna ni o dẹ wa tun jẹ Apena Ipẹru nigbati nwọn ro rere ti o ṣe si ilu Ipẹru nigba ogun Agbala ti awọn ara Ibadan gbe wa si Ipẹru. Ohun ti o yẹ ara Ipẹru ati ara Ogere ni lati ṣe ninu ọtẹ ti o wa ni ilu Ode ni ile Rẹmọ o yẹ ki wọn ṣe atunṣe larin ara wọn daradara. Awon ara Ipẹru nkọ orin kan wipe, "ojudun ọdẹ be ogẹwọ ọmọ re mọpọn o o bawa ti ma ṣewe si o, be ojudun ọdẹ ariwo ta ni Jẹbu-ode."

Emi ni tiyin nitotọ,
J. A. O. SHOMADE.

---

## *Olusakin's Column.*

ỌLUṢAKIN wishes all the readers of *Eko Akete* and everybody A Merry Christmas in advance and all good things.

---

### ORDINATION OF PRIESTS AND DEACONS AT ST. PAUL'S CHURCH, BREADFRUIT, LAGOS.

St. Paul's Church Breadfruit was crowded to the utmost capacity on Sunday the 16th December, 1928, at 10 a.m., when the Ordination of Messrs. E. T. Babatunde, D. A. Adenuga, J. O. Adeniran, E. A. Adigun and J. B, Fayemi, to the order of Deacons, and Rev. B. A. Falode and D. K. Asekun to Priesthood took place. The Revs. A. B. Akinyẹle, M.A., Principal, Ibadan Grammar School, preached the Ordination Sermon. His text was—"When thou art converted, strengthen thy brethren," which was properly dealt with by him.

Immediate after the service, the ordination ceremony began when the Venerable Archdeacon

of Lagos, T. A. J. Ogunbiyi, L.th., presented the candidates and read the Litany from memory. The Rev. James Jameison Pearse Lth., read the epistle and the gospel by Rev. E. T. Babatunde.

The Chancellor of the Diocese, Mr. Henry Carr, M.A., B.C.L., I.S.O., in his gorgeous robe of Office was in attendance.

The Rt. Rev. Bishop I. Oluwọle, B.A., D.D., assisted by the Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, Revs. James Jameison Pearse, M. S. Cole, H. V. E. Johnson, S. V. Latunde, J. H. A. Ogunro, W. O. Aiyedun, A. B. Akinyẹle, C. A. Ṣowunmi and J. O. Lucas officiated. We congratulate them all. Ki Oluwa ko mu ẹsẹ wọn duro ninu Ọgba Ajara Rẹ. Amin.

### Many Happy Returns of the Day.

Our heartiest congratulations to Mr. S. Ayọdele Thomas, Barrister-at-Law and Solicitor, for celebrating 45 Anniversary of his Birthday on Tuesday the 18th December, 1928. Ki Oluwa ko fi ọdun ọpọlọpọ han ẹ.

### Open Letters—Pertinent and Impertinent.

To Lord Banbury, House of Lords,
Westminster.

Dear Lord Banbury,—I am entertained by your statement in the House that most of the legislation which has been passed during the last twenty years has been bad legislation. You certainly ought to know, for you have put up your back against most of it. As Sir Frederick Banbury, Member for the City of London, you were the hottest stuff in opposing everything proposed by everybody that the House of Commons has ever known. You passed round more mustard and pepper than any M.P. in my experience, anyway. Glad to see you such a youngster for such an oldster.

*John Blunt.*

To Sir Robert Sanders, M.P.,
Minister of the Interior,
House of Commons.

My dear Bob,—Hereby receive my congratulations on your election as Chairman of the Kitchen Committee of the House of Commons. These chops and changes will occur, and I trust you will kitch in such a way as not to make a hash of the job. I note, by the way, that Miss Ellen Wilkinson has won her point that all M.P.s should be allowed to entertain women friends in the strangers' dinning-room. It is a tremendous innovation. I advise you to prepare for a crush.—*John Blunt, 1/12/28.*

### Mr. A. C. Burns, C.M.G.

**To be Deputy Chief Secretary to the Government.**

It is stated on good authority that Mr. A. C. Burns, C.M.G., Colonial Secretary, Bahamas, has been promoted to the appointment of Deputy Chief Secretary, Nigeria, in the place of Mr. H. M.-M Moore, transferred to Kenya.

### Deaths from Aspirin.

An inquest was held the other day on Frederick J. Bowles, of Tooting, who died after taking aspirin. We drew attention to the perils of this drug in its impure state a few weeks ago. It is time the authorities looked into the matter.—*John Blunt, 24/11/28.*

### Father's Plea for Mercy to his Son who Assaulted him.

Q. J. Marquis, 50 years of age, who was charged before H. A. Young, Esq., K.C., Police Magistrate, Lagos, on Monday, the 10th instant, with assaulting his father reported in the *Eko Akete* of last week was brought before the Magistrate on Monday the 17th December.

The complainant, an old man of about 80 years got up and asked the Court for mercy for the accused who was his son.

The Magistrate then said to the accused that had it not been that the complainant had asked for mercy on behalf of his son, he would have sent him to goal. The accused was therefore bound over, and ordered to leave his father's house to avoid a repetition of the occurrence.

### Another Son of the Oni of Ife in King's College, Lagos

We congratulate Master Joseph Ademuliyi, Son of the Ọni of Ifẹ who gained an admission in passing Medical Scholarship examination of the King's College, Lagos. We say to his guardian Mr. E. A. Oluyẹle Bright and to his Brother Prince E. A. Adeyẹmi—Ẹ ku ori re.

OLUṢAKIN.

### IDUPẸ.

A dupẹ lọwọ awọn Ọgbẹni A. Kessler, *Lagos Daily News* ati Adeniji Olugbile fun Iwe Ikajọ-oṣu ọdun 1929 ti nwọn ṣọwọ si wa.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## Use Yaro for your baby!

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## Increased health for 3/- only.

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers.

Price 3/- per bottle.

## A chance for female sufferers.

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs. cockroaches, etc., etc 1/- and 1/6d per bottle.

### Anti-Gon Pills.

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills--a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
27, Moloney Bridge Street
109, Griffith Street. Ebute Metta

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işẹ ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.

41, Offin Road, Lagos.

*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.

Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.

41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISOYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILN ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same,* if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

## TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

**A. B. Williams.**
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmi.. ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọj.. si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.